Ìjọsìn Tó Ní Ìtẹ́wọ́gbà Ọlọ́run (Apá 1)

A gbé e ka orí 15 nínú ìwé *Kí Ni Bíbélì Fi Kọni Gan-an?* ó wà lórí ìkànnì www.jw.org/yo.

OHUN TÍ O FẸ́ ṢE: Ṣàyẹ̀wò ohun tó o gbà gbọ́ àti ìdí tó o fi gbà á gbọ́, wo ohun tí Bíbélì fi kọni, kó o sì mọ bí wàá ṣe ṣàlàyé àwọn ohun tí o gbà gbọ́ fún àwọn ẹlòmíì.

ṢÉ GBOGBO ÌSÌN NI ỌLỌ́RUN FỌWỌ́ SÍ?

1 ṢÀYẸ̀WÒ OHUN TÓ O GBÀ GBỌ́

Kí ló lè mú káwọn kan dáhùn pé bẹ́ẹ̀ ni?

Kí ló lè mú káwọn kan dáhùn pé rárá?

Kí ni **ìwọ** rò nípa rẹ̀?

Kí nìdí tó o fi gbà bẹ́ẹ̀?

www.jw.org © 2016 Watch Tower Bible and Tract Society of Pennsylvania

2 WO OHUN TÍ BÍBÉLÌ FI KỌ́NI

A gbọ́dọ̀ jọ́sìn Ọlọ́run lọ́nà tó fẹ́wọ́ sí.

(Wo orí 15 nínú ìwé *Bíbélì Fi Kọ́ni,* ìpínrọ̀ 1 sí 4.)

Ka Mátiù 7:21-23.

Bí Jésù ṣe sọ, kí nìdí tó fi jẹ́ pé ká kàn **sọ** pé a gba Jésù tàbí bàbá rẹ̀ gbọ́ nìkan kò tó?

Ka Mátiù 7:13, 14.

Kí nìdí tí kò fi yẹ kó yà wá lẹ́nu pé ọ̀pọ̀lọpọ̀ èèyàn ni kò tíì rí ìsìn tòótọ́?



Tá a bá ti mọ bí owó gidi ṣe ń rí, á rọrùn láti dá ayédèrú owó mọ̀. Lọ́nà kan náà, tá a bá mọ bá a ṣe lè dá ìsìn tòótọ́ mọ̀, á rọrùn fún wa láti mọ ìsìn èké

www.jw.org © 2016 Watch Tower Bible and Tract Society of Pennsylvania

Ìwà àwọn tó ń ṣe ìsìn tòótọ́ àti ohun tí wọ́n gbà gbọ́ máań fi hàn pé ìsìn tòótọ́ ni wọ́n ń ṣe.

(Wo orí 15 nínú ìwé *Bíbélì Fi Kọ́ni,* ìpínrọ̀ 5 sí 14.)

Ka Sáàmù 83:18, Mátíù 20:28 àti 2 Tímótì 3:16, 17.
Kí làwọn Kristẹni tòótọ́ gbà gbọ́ nípa Ọlọ́run, Jésù àti Bíbélì?

Ka Mátíù 24:14, Máàkù 12:17 àti Jòhánù 13:35.
Báwo làwọn èèyàn Ọlọ́run ṣe ń fi hàn nínú ìgbésí ayé wọn ojoojúmọ́ pé ìsìn tòótọ́ làwọn ń ṣe?

Kí ló mú kó dá **ẹ** lójú pé àwọn Ẹlẹ́rìí Jèhófà ló ń ṣe ìsìn tòótọ́?

www.jw.org © 2016 Watch Tower Bible and Tract Society of Pennsylvania

3 ṢÀLÀYÉ ÀWỌN OHUN TÍ O GBÀ GBỌ́

TÍ ẸNÌ KAN BÁ SỌ PÉ…

Gbogbo ẹ̀sìn ló ní èèyàn rere láàárín wọn.

O LÈ SỌ PÉ…

Òótọ́ ni pé *àwọn èèyàn* tó lọ́kàn rere wà nínú gbogbo ẹ̀sìn. Àmọ́ mo gbà pé ẹ̀sìn kan ṣoṣo ni Ọlọ́run tẹ́wọ́ gbà, torí pé…

_____

_____

Ẹsẹ Ìwé Mímọ́ wo lo máa kà fún ẹni náà?

_____

Tó o bá fi èrò ẹni náà sọ́kàn, báwo lo ṣe máa ṣàlàyé ẹsẹ Ìwé Mímọ́ náà fún un?

_____

TÍ ẸNÌ KAN BÁ SỌ PÉ…

Ẹ̀sìn mi wà lára ẹ̀sìn táwọn èèyàn ń ṣe jù láyé. A ò lè sọ pé adúrú àwọn èèyàn yẹn ti ṣìnà kẹ̀.

O LÈ SỌ PÉ…

Ọ̀pọ̀ èèyàn ló ṣeé ṣe kí wọ́n gbà pẹ̀lú ẹ. Àmọ́ ohun tí mo gbà gbọ́ yàtọ̀ síyẹn torí pé…

_____

_____

Ẹsẹ Ìwé Mímọ́ wo lo máa kà fún ẹni náà?

_____

Tó o bá fi èrò ẹni náà sọ́kàn, báwo lo ṣe máa ṣàlàyé ẹsẹ Ìwé Mímọ́ náà fún un?

_____

www.jw.org © 2016 Watch Tower Bible and Tract Society of Pennsylvania